E MA KA IRO-
HIN IMOLE KI
E SI MA POLO-
WO OJA YIN
SINU RE

# IRỌHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arofo ti -:
ANỌYIN LOHUN-
BI-ỌMỌGE- IMARO
APA KETA
LATI ỌWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postag Extra

VOL. I No. 39, WEDNESDAY MARCH 26, — APRIL 1, 1958 KỌBỌ KAN

# ILE "ILORIN" YIO KURO LABE AJAGA FULANI

Lehin ti awon Oluwadi oro ti rin soke, rin sodo larin ile Naijiria, kini ohun ti o mba awon eya ti ko po tobe leru ti nwon ko fi ni nigboiya lati se ododo, NIGBATI NWỌN BA GBA OMINIRA TAN, NWỌN TUN PADA BỌ SI EKO LATI WA GBỌ LẸNU AWỌF AṢOJU AWỌN AGBEGBE MẸTẸTA NWỌN-YI, ILE YORUBA, ILẸ IBO ATI ILẸ HAUSA, KI-NI OFIN TI NWỌN LE FI JẸRI ỌRỌ WỌN ?



OLOYE ROTIMI WILLIAMS

Oloye Rotimi Williams rọ wipe, ọrọ kan ti on tun fẹ fi kun ọrọ pipa ilẹ Ilọrin mọ ilẹ Yoruba ni wipe lẹhin ti oluwadi ba ti ri wipe, o tọ ki Ilọrin papọ mọ ilẹ Yoruba yoku, o yẹ ki nwọn tun pinnu ẹnu ala ilẹ Hausa ati ti Yoruba, ki o ma ba si gbọnmisi-omi-koto.

Nitoripe tẹlẹ-tẹlẹ, awọn Ilọrin a t i awọn Kabba, Yoruba ni nwọn nṣe lati ipilẹṣẹ ati lati ọdun 1897 ni nwọn ti mbẹ fun a r a wọn. Aṣoju ilẹ Hausu tako ọro yi, o wipe, bi nwọn ba tile gba ilẹ Ilọrin kuro labẹ Hausa, ko si ọrọ wipe ki a din ẹnu ala ilẹ Hausa ku ninu ọrọ oluwadi, ko tilẹ ti si idi ọrọ pe Ilọrin ni latı kuro labẹ Hausa.

## OLOYE AKINTOLA BA AWON OSISE RE SORO

Enlti a nwo ninu aworan yi ni Oloye S. L. Akintọla, awọn oṣiṣẹ rẹ ni nwọn binu da iṣẹ silẹ laipẹ yi larapa o ṣe owo koṣe owo.

Ṣugbọn nipa ọgbọn ati lakaye Ọloye yi, o mu ki awọn oṣiṣẹ rẹ tun pada si ẹnu iṣẹ.

Laipẹ yi ni ọrọ pilẹ ni pẹrẹwu larin awujọ awọn oṣiṣẹ na ati awọn alakoso ibiṣẹ Post and Telegraph, nwọn fi ọrọ we ọrọ, nwọn si sọ ẹdun ọkan wọn fun alaṣẹ gbọ.

Ninu ọrọ ohun ti o ndun awọn oṣiṣẹ na ni ọrọ owo oṣu awọn ti o npin iwe kakiri, awọn ti o npin waya kiri, awọn ti o nko iwe kakiri ti owo oṣu wọn kere.

Ọrọ tọtun tosi dara, ṣugbọn nwọn koiti fi ori ọrọ na ti sibikan.



Oloye S. L. Akintọla

Ẹ MA KA IWE IROHIN IMỌLẸ, KI Ẹ SI MA POLOWO ỌJA NYIN SINU RẸ.

AWON IWE KOSEMANI

Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Ẹsin Ojisẹ nla Muhammad 3/6d
Kurani Esumẹta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu mẹrindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan a ti Nofila Oru Oṣu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbẹyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun 5/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Iṣẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Iwe Itumọ Ala ati Ami Ara 3/6d
Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 2/6d

Akiyesi:- Ọpọlọpọ onibara wa ni ko mọ ile-iṣẹ wa ni Mushin, a fi eyi si eti igbọ wọn pe ki wọn ma lọ ra POSTAL ORDER ni POST OFFICE pẹlu Stamp 1/- ki wọn fi ranṣẹ si wa, nwọn yio si ri ọja wọngba kiakia.

Fi owo ati Stamp 1/- ranṣẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtt
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin,

# IMOLE !!

ẸBIN ỌRỌ WA:- IMOLE DE OKUNKỌN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*

**16, Bamgbose Street, Lgos**

**Telephone:- 21985**

*London Office:-*

*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

UNITED KINGDOM REPRESENTATIVE

PUBLISHING DISTRIBUTING CO. LTD. MITRE HOUSE

177, Regent Street, London W. 1.

FUN OWO "IROHIN IMỌLẸ" ODUN KAN

EKO— Ṣile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d)

Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Ṣile Mefa ati Kọbọ Mẹfa (6/6d)


# EFIN NI IWA

Pupọ ninu wa ti o ba nlọ si ṣọbu kakiri lati lọ ra ohun elo yio gba awa oniwe yi gbọ wipe ododo ni ọrọ wa.

Nigbagbogbo ti enia ba lọ ra ọja ni ṣọbu ti enia ba wo bi awon ti yio ta ọja na yio ti se, yio wipe oun ko fe mo, pupo igba si ni awọn ti o nta oja wonyi ko mọ ọrọ lati ba onibara sọ, nigbamiran ẹwẹ nwon ma ngbe bi wọn ti to nile wọn wa sile iṣẹ lati wa fi ta ọja, iwonyi ko tọ rara, ọrọ Bibeli sọ bayi pe ohunkohun ti ọwọ re ba ba lati ṣe ṣee tọkantọkan, nipa eyi ti enia ba ni owo-nile ko to fun lati lo jẹ sa (Sir) labẹ enikẹni, ti o ba si wa nile rẹ, kosi eniti yio ri oluware lati pe pe ki o wa ta oja fun oun.

Dajudaju ẹnkẹni ti o ba lọ ra oja tabi kio lọ fun alaye lọdọ ọyinbo ibase okunrin ni tabi obinrin, oluwarẹ yio mọ daju wipe yeye ni awọn ọmọ wa lọkunrin ati lobinrin ti nwọn wa nibi iṣẹ nṣe.

Eyi mu wa ranti ọjọ kan nile iṣẹ Kingsway Stores arakunrin kan fẹ ra ọja, ọja ti o si fẹ ra jẹ Sokoto fun awọn ọmọ rẹ ọkunrin ti nwọn ko ju ọmọ ọdun marun lọ o ṣi nbere lọwọ arabinrin o wa nibẹ irufe iwọn (size) ti yio dara fun awọn ọmọ na dipo ki arabinrin ṣe alaye fun un iṣe ni o bere si fi oyinbo bu arakunrin na, ko wa mọ wipe arakuurin na gbo oyinbo rara ninu oyihbo rẹ ti sọ ni ọjọ na wipe "Ti nwọn ba ti ri enia ti o wa sisẹ, nwọn ṣi ro wipe ebi ni o npa" nibe ni arakunrin na ti dalohun wipe "Ohunkohun ti o ba ja mọ iyẹn ninu ile re ni o mọ ṣugbọn o wa fun iṣẹ ni, o si gbọdọ see tabi ki o gbe ile rẹ". Nipa eyi ale sọ wipe o tọ osi ye ki awọn ọmọ wa lọkunrin ati lobinrin kọ ọpọlọpọ ẹkọ lati ọdọ awọn oyinbo ki nwon si mọ daju pe ninu tọrọ, kobo ti awọn onibara wa nra ninu re na ni nwọn ti nri owo oṣu san.

Ti ko ba je wipe awọn wọnyi ko nhu irufe iwa bayi nile won, nwon ko ma foju di enikeni ti o ba ra ọja tabi ti o fe bere.


DIRECT YOUR PRINTING JOBS TO:-

MODUPE PRINTING PRESS

16, Bamgboṣe Street, Phone 21985

LAGOS.


# Iwe Si Olotu

## Idahun Si Ibere Ogbeni Suberu Owolarafe

Olotu,

Inu mi yio dun pupọ bi e ba le gbami laye lati fun Ọgbẹni Seberu Owolarafẹ ni esi nkan ti o bere ninu iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ karun oṣu yi.

Emi ko sọpe esi ti mo fẹ sọ yi ni o dara ju, ṣugbọn eyiti o yẹ ni oju emi ni ngo sọ, ntori aisọrọ yan ọrọ ni o npa elepe, iṣaju toni Igba wuwo ju awo lọ, toto o ṣe bi owe o.

Nkan kini ti Ọgbẹni na bere nipe :- Ninu ẹniti o fun enia ni ile lati gbe ati ẹniti o ba enia wa ọna iṣẹ lati ṣe ati ẹniti o fẹ Iyawo fun enia, ewo ni o dara ju?

Loju ti emi ẹni ti o ba enia wa ọna iṣẹ ni o tobi ju, nitori enia ti o nṣe iṣẹ o ni lati gba owo bi ko tilẹ pọ, ẹniti o ba dẹ ni owo, o le fi kọle ki o ma gbe, o dẹ le fi owo gbe Iyawo. Nitori mori enia ti o ni owo ti iwa rẹ dẹ buru pupọ. ṣugbọn ntoripe o ni owo, on ni awọn enia npe ni enia dada. Ẹyin ọrẹ mi, " Iṣe ni ogun iṣẹ "

Ibere keji nipe enia nlọ si ile ana rẹ, o lọ ya ẹwu ẹtu ki o le niyi lọdọ ana re, ṣugbọn nigbati o de ile ana o ni oru nmu on, o bọ aṣọ rẹ, o fi kọ si ibikan, ṣugbọn ibiti awọn ara ile ti nlọ ti wọn nbọ, wọn ṣesi re aṣọ rẹ nisu epo, kini o yẹ ki o ṣe ?

Loju ti emi, nitori ki o le niyi ni ile ana rẹ ni o fi lọ ya ẹwu ẹtu, o si ṣoro fun ki o to sọpe ki wọn fun on ni omiran afi ti o ba fẹ tẹ loku, gẹgẹ bi o ti tọ ati bi o ti yẹ, nkan ti alaṣọ bani ki o ṣe ni oni latl ṣe, nitori ohun ti oju wa loju, a ki fuyẹ ki a sọ pe awuwo o.

E ṣe aye ti ẹ gba mi o.<br>Emi ni ti yin toto<br>Samuel Olayide Adeoye.

AWỌN TI IDAHUN WỌN DỌGBA<br>A. O. Phillips<br>15, Igbẹhin-Adun Street,<br>Odi-Olowo, Mushin.<br>A. F. B. Anifaloyi<br>Otun-Oro.<br>R. A. Bello<br>Ilala Igbomina

ẹdun ọkan mi yi ba awọn onkawe Imọlẹ sọrọ. Ita na lọ ba yi:— Baba kan ni iyawo mẹta, ni ọjọ kan wọn mura lati lọsi ileto kan nigbati wọn de arin ọna, wọn sọ wipe orẹ awọn awọn fẹ simi diẹ, bi wọn ti sọkalẹ ni baba fi ẹhin lelẹ ti osun lọ, nigbati ose diẹ ni awọn iyawo ji baba pe ẹjẹ ki a lọ, aso baba ti ku wọn ji baba fun ọpọlọpọ igba, sugbọn o ti ku, ni awọn iyawo wọnyi ba sun ẹkun diẹ, eyi iyawo ti o wa ni arin bafo sanlẹ wipe kini ati se eyi si, on na si ku, ipawo kekere sare wa onisegun lọ, iyale wọn ni on yio duro ti ohunkohun ti yio ba se, seju onini yio se, oni bi eiye lofẹ yọ oju rẹ ni o, yio yọ ti on pẹlu

Ni iyale ba duao ti oku awọn mejeji, eyi iyawo kekere ba pada de pẹlu onisegun, ni oba ji baba pelu iyawo ti oku pẹlu rẹ ni baba ba dupẹ lọwọ onisegun, oṣi dupẹ lọwọ Ọlọrun. Obere lọwọ baba onisegun pe kini o fẹ ki nfun ọ nitori isẹ nla ti ose yi? onisegun na wipe on ko ni gba owo, bẹni on ko gba asọ, sugbọn on yio gba ọkan ninu awọn iyawo re mẹteta.

Ẹnyin onkawe wa, ewo loyẹ ki baba na fun onisegun ninu awọn iyawo rẹ na? Ẹtete laye mi o ki nle tete lọsọ fun baba na.

Olotu modupẹ aye ti ẹ gba mi, iwaju ni ọpa ẹbiti re si.

Emi ni:-<br>J. A. Adeyẹmi<br>Iludun Ọtun-Oro.

## Ela Eyi Yemi

### Baba ti oni Iyawo meta

Inu mi yio dun bi olotu bale gbami laye lati fi


E ma ka Iwe Irohin Imole, O kun fun Itan Aladun ati eyiti o mu Ogbon wa, Ki e si ma Polowo Oja yin sinu re.

